pupọ ninu Kristi lati paṣẹ ohun ti o yẹ fun ọ,

9. Ṣugbọn nitori ifẹ emi kúkú bẹ̀bẹ̀, iru ẹni bi emi Paulu arugbo, ati nisinsinyìí òndè Kristi Jesu pẹlu.

10. Emi bẹ ọ nitori ọmọ mi, Onesimu, ti mo bí ninu ìdè mi: (Kol 4:9; 1 Kor 4:14,15.)

11. (Nigba kan ri ẹni ti o jẹ alâìlere fun ọ, ṣugbọn nisinsinyìí o lérè fun ọ ati fun mi:)·

12. Ẹni ti mo rán padà, ani, ọkàn emi tikarami ni mo rán yìí.

13. Ẹni ti emi ìbá fẹ daduro pẹlu mi, ki o lè maa ṣe iranṣẹ fun mi ni ipo rẹ ninu ìdè ihinrere. (Filp 1:7.)

14. Ṣugbọn ni àìmọ̀ inu rẹ emi kò fẹ́ ṣe ohun kan; ki oore rẹ má baa dabi ifagbáraṣe, bikoṣe tìfẹ́tìfẹ́ (1 Pet 5:2; 2 Kor 9:7.)

15. Nitori boya idi rẹ̀ nì yìí ti o fi kuro lọdọ rẹ fun igba diẹ, ki iwọ baa lè ni i titi lae;

16. Ki i ṣe bi ẹrú mọ́, ṣugbọn ó ju ẹru lọ, arakunrin olufẹ, paapaa fun mi, melomelo ni fun ọ, pẹlu, nipa ti ara ati nipa ti Oluwa? (Matt 23:8; 1 Tim 6:2; Kol 3:22.)

17. Nitori naa bi iwọ bá kà mi si ẹlẹgbẹ rẹ, gba a bi emi tikarami. (2 Kor 8:23.)

18. Ṣugbọn bi o bá ti ṣẹ̀ ọ́ rárá, tabi o ti jẹ ọ nigbèsè kan, kaa si mi lọ́rùn.

19. Emi Paulu ni o fi ọwọ ara mi kọ ọ́, emi o san an pada: lai tilẹ̀ ni sọ ohunkohun nipa jíjẹ ti o jẹ mi nigbèsè ara iwọ tikararẹ.

20. Nitootọ́, arakunrin, jẹ ki emi ni ayọ̀ rẹ ninu Oluwa: tu ọkàn mi lara ninu Kristi.

21. Bi mo ti ni igbẹkẹle ni igbọran rẹ ni mo fi kọ̀wé si ọ: nitori mo mọ̀ pe, iwọ o tilẹ̀ ṣe ju bi mo ti wí lọ. (2 Kor 2:3.)

22. Ati pẹlu, pèsè iyara àlejò silẹ dè mí; nitori mo gbẹkẹle pe nipa adura yin, a o fi mi fun yin. (A.A. 28:23; Filp 1:25; 2:24; 2 Kor 1:11.)

**Ìkíni ati Oore-ọfẹ.**

23. Epafra, òndè ẹlẹgbẹ mi ninu Kristi Jesu ki ọ; (Kol 1:7.)

24. Marku, Aristarku, Dema, Luku, awọn olubaṣiṣẹ mi ki ọ pẹlu. (A.A. 12:12; Kol 4:10.)

25. Oore-ọfẹ Jesu Kristi Oluwa wa wà pẹlu ẹmi yin. Amin. (2 Tim 4:22.)

58

# AWỌN HEBERU

**(A.D. 64)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Iṣáaju: Kristi ẹni ìfihàn ìkẹhìn ti Ọlọrun.**

OLỌRUN ẹni, ni ìgbà pupọ ati ni oníruurú ọ̀nà, ti ipa awọn wòlì ba awọn baba wa sọ̀rọ̀ ni igba àtijọ́.

2. Ni ọjọ́ ìkẹhìn wọnyìí o tí ipasè ọmọ rẹ̀ bá wa sọ̀rọ̀, ẹni ti o fi ṣe ajogún ohun gbogbo, nipasè ẹni ti o dá awọn ayé pẹlu; (Gal 4:4; Heb 2:3; Psm 2:8; Jhn 1:3; 1 Kor 8:6.)

3. Eni ti i ṣe ìtànṣán ogo rẹ̀, ati aworan oun tìkárarẹ̀, ti o sì nfi ọ̀rọ̀ agbara rẹ̀ mu ohun gbogbo dúró. Lẹhìn ti o ti ṣe ìwẹ̀nùmọ́ ẹ̀ṣẹ̀, o jokòó lọwọ ọ̀tún Ọlanla ni òkè; (Jhn 1:14; Kol 1:17; Heb 7:27; 8:1.)

**Kristi Ọmọ Ọlọrun sàn ju awọn Angeli lọ.**

4. O si ti fi bẹẹ di ẹni ti o sàn ju awọn angẹli lọ, bi o ti jogún orukọ ti o ta tiwọn yọ. (Ef 1:21; Filp 2:9,10; Jhn 17:4–5.)

5. Nitori èwo ninu awọn angẹli ni o

wi fun ri pé, "Iwọ ni Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ?" Ati pẹlu, "Emi yoò jẹ́ Baba fún un, oun yoo sì jẹ Ọmọ fun mi? (Psm 2:7.)

6. Ati pẹlu, nigba ti o mu akọbi naà wá sí ayé, o wi pe, "Ki gbogbo awọn angẹli Ọlọrun foribalẹ̀ fún un." (Heb 10:5; Deut 32:43.)

7. Ati níti awọn angẹli, o wi pe, "Ẹni ti o dá angẹli rẹ̀ ni ẹ̀mí, ati awọn iranṣẹ rẹ̀ ni ọ̀wọ́ iná." (Psm 104:4.)

8. Ṣugbọn niti Ọmọ ni o wi pe, "Ìtẹ́ rẹ, Ọlọrun, lae ati laelae ni; ọ̀pá alade ododo ni ọ̀pá alade ijọba rẹ. (Psm 45:6,7.)

9. Iwọ fẹ́ ododo, iwọ si korira ẹ̀ṣẹ̀; nitori naà ní Ọlọrun, àní Ọlọrun rẹ, ṣe fi òróró ayọ̀ yàn ọ ju awọn ẹlẹgbẹ rẹ lọ."(Filp 2:9; Isa 61:1,3.)

10. Ati "Iwọ, Oluwa, ni àtètèkọ́ṣé ni o tí fí ipilẹ ayé sọlẹ̀; awọn ọ̀run si ni iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀; (Psm 102:25.)

11. Wọ́n o ṣègbé, ṣugbọn iwọ yoo wà sibẹ, gbogbo wọn ni yoò si gbó bi ẹ̀wù; (Isa 34:4; Psm 102:26;27.)

12. Ati bi aṣọ ni iwọ yoo ká wọn, a o sì pàrọ̀ wọn: ṣugbọn bakannaa ni iwọ, ọdun rẹ ki yoò sì pin." (Heb 13:8.)

13. Ṣugbọn èwo ninu awọn angẹli ní o sọ nipa rẹ̀ pé, "Jókòó ni ọwọ́ ọ̀tún mi, títí emi o fi sọ awọn ọ̀tá rẹ di apoti itìsẹ̀ rẹ?" (Psm 110:1; Heb 10:13.)

14. Ki ha ṣe ẹ̀mí ti njiṣẹ ni gbogbo wọn jẹ́, ti a rán lati maa ṣe iranṣẹ nitori awọn ti o jẹ́ ajogún igbàlà? (Psm 103:20; Heb 5:9.)

## ORI 2.

**Ìkìlọ̀ nipa kikọ ifihan Ọlọrun.**

NITORI naà o yẹ ti awa iba maá fi ìyè gidigidi si ohun wọnyìí ti awa ti gbọ́, ki a má ba gbá wá lọ kúrò ninu wọn nigbakan.

2. Nitori bi ọ̀rọ̀ ti a ti ẹnu awọn angẹli sọ ba duro ṣinṣin, ati tí olukuluku irekọja ati aigbọran si gba ẹ̀san ti o tọ́; (Heb 1:1; A.A. 7:53; Heb 10:28,35.)

3. Awa o ti ṣe là, bi awa kò ba nani irú igbala nla bi èyí? Ti a kọ́kọ́ bẹrẹ si sọ lati ọ̀dọ̀ Oluwa, ti a si fi ẹ̀rí rẹ̀ mulẹ̀ fun wa lati ọdọ awọn ẹni tí ó gbọ́; (Heb 10:29; 1:1; Luk 1:2.)

4. Ọlọrun si nfi iṣẹ́-àmì ati iṣẹ́ iyanu, ati oniruuru iṣẹ́ agbara, ati ẹ̀bùn Ẹmi Mimọ bá wọn jẹri gẹgẹ bi ìfẹ́ rẹ̀? (Jhn 4:48; 1 Kor 12:4; Ef 1:5.)

**Kristi ni a fi ijọba ọ̀run fún.**

5. Nitori pe kìi ṣe abẹ́ awọn angẹli ni Ọlọrun fi ayé ti nbẹ ti awa nsọrọ rẹ̀ si. (Heb 6:5.)

6. Ṣugbọn ẹnikan sọ nibikan pé, "Kinni eniyan ti iwọ fi nṣe iranti rẹ̀, tabi ọmọ eniyan, ti iwọ fi nbẹ̀ ẹ́ wò? (Psm 8:4–6.)

7. Iwọ dá á rẹlẹ̀ diẹ ju awọn angẹli lọ; iwọ fi ogo ati ọlá de e ni adé, iwọ si fi í jẹ olori iṣẹ́ ọwọ́ rẹ:

8. Iwọ fi ohun gbogbo sabẹ ẹsẹ̀ rẹ̀:" Nitori niti pé o fi ohun gbogbo sabẹ rẹ̀, kò ku ohun kan ti kò fi sábẹ́ rẹ̀. Ṣugbọn nisinsinyìí awa kò ì tí rli pé a fi ohun gbogbo sábẹ́ rẹ̀. (Matt 28:18; 1 Kro 15:27; 15:25.)

9. Awa rí ẹni ti a dá rẹlẹ̀ diẹ ju awọn angẹli lọ, àní Jesu, ẹni tí a fi ogo ati ọlá dé ni adé nitori ìjìyà ikú; ki o le tọ ikú wò fún olukuluku eniyan nipa ooreọfẹ Ọlọrun. (Filp 2:7–9; A.A. 2:33; Jhn 3:16; 1 Jhn 2:2.)

**Kristi gẹgẹ bi ẹni otitọ.**

10. Nitori pé o yẹ fun un, nitori ẹni ti ohun gbogbo ṣe wà, ati nipasẹ ẹni tí ohun gbogbo wà, ní mímú awọn ọmọ pupọ wá sinu ogo, lati ṣe Balogun igbàlà wọn ni aṣepé nipa ìjìyà. (Luk 24:46; Rom 11:36; A.A. 3:15; 5:31; Luk 13:32.)

11. Nitori ati ẹni tí nsọ ni di mímọ́ ati awọn tí a nsọ di mímọ́, lati ọ̀dọ̀ ẹnikanṣoṣo ni gbogbo wọn ti wá: nitori èyí ni kò ṣe tijú lati pè wọ́n ni arakunrin. (Heb 10:10; A.A. 17:26; Jhn 20:17.)

12. Wí pé, "Emi o sọ̀rọ̀ orukọ rẹ fun

awọn ará mi, ni àárin ìjọ lemi o kọrin ìyìn rẹ." (Psm 22:22.)

13. Ati pẹlu, "Emi o gbe igbẹkẹle mi lé e." Ati pẹlu, "Kiyesi í, emi ati awọn ọmọ ti Ọlọrun fifun mi." (Isa 8:17,18; Jhn 10:29.)

**Kristi ẹni ti a fi rúbọ fun gbogbo eniyan.**

14. Njẹ ni ìwọ̀n bi awọn ọmọ ti ṣe alabapin ara ati ẹ̀jẹ̀, bẹ̀ẹ gẹgẹ ni oun pẹlu sì ṣe alabapin ninu ohun kannaà; ki o le ti ipa ikú pa ẹni ti o ní agbara ikú run, èyí ni Èṣù; (Matt 16:17; Jhn 1:14; 1 Kro 15:54–57; 1 Jhn 3:8.)

15. Ki o si lè gba gbogbo awọn ti o titori ìbẹ̀rù ikú wà labẹ ìdè lọjọ ayé wọn gbogbo (Rom 8:15; 2 Tim 1:7.)

16. Nitori pé, nitootọ ki í ṣe awọn angẹli ni o ṣe ìrànlọ́wọ́ fún, ṣugbọn irú-ọmọ Abrahamu ni o ṣe iranlọwọ fún.

17. Nitori náà ó yẹ pé ninu ohun gbogbo ki o dabi awọn ará rẹ̀, ki o le jẹ alaanu ati olootọ Olori Alufa ninu ohun ti i ṣe ti Ọlọrun, ki o lè ṣe ètùtù fun ẹ̀ṣẹ̀ awọn eniyan. (Filp 2:7; Heb 4:15; 5:1,2;1 Jhn 2:2; 4:10.)

18. Nitori níwọ̀n bi oun tikararẹ ti jìyà nipa ìdánwò, o lè ran awọn tí a ndan-wo lọ́wọ́. (Heb 4:15.)

## ORI 3.

**Jesu, bi Oluwa, pọ ju Mose, Iranṣẹ.**

NITORI naà ẹyin ará mimọ, alabapin ìpè ọ̀run, ẹ gba ti Aposteli ati Olori Alufa ijẹwọ wa rò, àní Jesu; (Heb 2:11; Filp 3:14; Rom 15:8; Heb 10:21.)

2. Ẹni tí o ṣe olootọ si ẹni tí o yàn an, bi Mose pẹlu ti ṣe ninu gbogbo ile (Ọlọrun) rẹ̀.

3. Nitori a ka ọkunrin yìí ni yiyẹ si ogo ju Mose lọ niwọn bi ẹni tí o kọ́ ile ti lọla ju ile lọ. (2 Kro 3:7–11.)

4. Lati ọwọ eniyan kan ni a sá ti kọ́ olukuluku ilé; ṣugbọn ẹni tí ó kọ́ ohun gbogbo ni Ọlọrun. (Ef 2:10; Heb 1:2.)

5. Mose nitootọ si ṣe olóotọ ninu gbogbo ile (Ọlọrun) rẹ̀, bi iranṣẹ, fun ẹ̀rí, ohun ti a o sọ̀rọ̀ wọn ni ìgbà ikẹhin; (Num 12:7; Eks 14:31; Deut 18:18,19.)

6. Ṣugbọn Kristi bi ọmọ lori ile (Ọlọrun) rẹ̀; ile ẹni ti awa jẹ́, bi awa ba di igbẹkẹle ati ìṣògo ìrètí wa mu ṣinṣin títí de òpin. (Heb 1:2; 1 Kor 3:16; Rom 5:2; Kol 1:23.)

**Ibi isinmi ti Jesu sàn ju ti Mose ati Joṣua lọ (Kenaani).**

7. Nitori naa gẹgẹ bi Ẹmi Mimọ ti wí, "Loni bi ẹyin bá gbọ ohùn rẹ̀, (Heb 9:8; Psm 95:7.)

8. Ẹ má ṣe sé ọkan yin le, bi ìgbà ìṣọ̀tẹ̀, bi lọjọ ìdánwo ní aginjù:

9. Nibi ti awọn baba yin dan mi wò, ti wọn si ri iṣẹ́ mi ni ogójì ọdún. (A.A. 7:36.)

10. Nitori naa a mu inú bi mi si ìran naa, mo si wi pé, 'Nigba gbogbo ni wọn ṣìnà ni ọkàn wọn; wọn kò sì mọ ọ̀nà mi.'

11. Bi mo ti bura ni ibinu mi, 'wọn ki yoo wọ inu isinmi mi.'" (Heb 4:3,5.)

**O ṣe pataki lati fi igbagbọ wọ ibi isinmi Jesu.**

12. Ẹ kiyesara, ará, kí ọkàn buburu ti aigbagbọ máṣe wà ninu ẹnikẹni yín, ni lílọ kúrò lọdọ Ọlọrun alàáyè. (Heb 12:25.)

13. Ṣugbọn ẹ maa gba ara yín niyanju lojoojumọ, niwọn igba ti a bá npè ni "Oní," Ki a ma ba à sé ọkàn ẹnikẹni ninu yín le nipa ẹ̀tàn ẹ̀ṣẹ̀. (Heb 10:24,25; Ef 4:22.)

14. Nitori awa di alabapin pẹlu Kristi, bi awa bá di ipilẹṣẹ igbẹkẹle wa mú ṣinṣin títí dé òpin; (ẹsẹ 6.)

15. Nigba ti a nwí pé, "Loni bi ẹyin ba gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ má ṣe sé ọkàn yin le, bi ìgbà ìmúnibínú." (ẹsẹ 17.)

16. Awọn tani o gbọ́ ti o si tún ṣọ̀tẹ̀? Ki ha ṣe gbogbo awọn ti o jade kuro ni Egipti labẹ akoso Mose? (Num 14:2.)

17. Awọn tani o sì binu sí fún ogoji

ọdún? Ki ha ṣe si awọn ti o dẹ̀ṣẹ̀, òkú awọn ti o sùn ní aginju? (Num 14:29; Psm 106:26.)

18. Awọn wo ni ó bura fun pé wọn kì yoò wọ inu isinmi oun, bi ko ṣe fún awọn tí ó ṣe aigbọran? (Num 14:23; Heb 4:6.)

19. Awa si ri pé wọn kò lè wọ inu rẹ̀ nitori aigbagbọ. (Jhn 3:36.)

ORI 4.

**Ìkìlọ̀ ki a má baa pàdánù ibi isinmi ti Jesu pèsè fun wa irú èyí tí a fi ilẹ̀ Kenaani ṣe apẹẹrẹ.**

NITORI naà, ẹ jẹ́ kí a bẹ̀rù, bi a ti fi ileri lati wọ inu isinmi rẹ̀ fun wa, ki ẹnikẹni ninu yín má ba a dabi ẹni pé o ti kùnà rẹ̀. (Heb 12:15.)

2. Nitori pé a ti waasu ihinrere fun wa gẹgẹ bi fun awọn naà, ṣugbọn ọ̀rọ̀ ti wọn gbọ́ kò ṣe wọn ni ire, nitori tí kò dàpọ̀ mọ́ ìgbàgbọ́ ninu awọn ti o gbọ ọ. (1 Tess 2:13.)

3. Nitori pé awa ti o ti gbagbọ wọ inu isinmi gẹgẹ bí ó ti wí, "Bi mo ti bura ninu ibinu mi, 'Wọn ki yoò wọ inu isinmi mi.'" bi o tilẹ jẹ pé a ti parí iṣẹ́ wọnyìí lati ìpilẹ̀ ayé. (Psm 95:11; Heb 3:11.)

4. Nitori ó ti sọ nibikan niti ọjọ́ keje bayìí pé, "Ọlọrun sì sinmi ní ọjọ́ keje kuro ninu iṣẹ́ rẹ̀ gbogbo." (Gen 2:2; Esk 20:11.)

5. Ati nihinyìí pẹlu ó wí pé, "Wọn ki yoò wọ inu isinmi mi." (Psm 95:11; Heb 3:11.)

6. Nitori naà bi o ti jẹ pé, ó kù ki awọn kan wọ inu rẹ̀, ati awọn ti a ti waasu ihinrere naà fun nişàaju kò wọ inú rẹ̀ nitori aigbọran: (Heb 3:18,19.)

7. Ati pé, ó yan ọjọ́ kan, o wi ninu Iwe Dafidi pe, "Loni," lẹhin ìgbà pípẹ́ bẹ́ẹ̀; bi a ti wi nişaaju, "Loni bi ẹyin ba gbọ́ ohùn rẹ̀, ẹ ma ṣe sé ọkàn yin le." (Psm 95:7,8; Heb 3:7,8.)

8. Nitori ibaşepe Joṣua ti fun wọn ni isinmi, oun ki ìbá ti sọ̀rọ̀ nipa ọjọ miran lẹhinnaà. (Jos 22:4; Heb 1:1.)

9. Nitori naa isinmi kan kù fún awọn eniyan Ọlọrun.

10. Nitori pé ẹni ti o ba bọ́ sinu isinmi rẹ̀, oun pẹlu sinmi kúrò ninu iṣẹ́ tirẹ̀, gẹgẹ bi Ọlọrun ti sinmi kuro ni tirẹ̀. (ẹsẹ 4.)

11. Nitori naà ẹ jẹ́ ki a mura gírí lati wọ inu isinmi naà, ki ẹnikẹni má baa ṣubú nipa irú aigbagbọ kannaà (Heb 3:18.)

12. Nitori ọ̀rọ̀ Ọlọrun yè, o si lagbara, o si mu ju idàkídà oloju-meji lọ, o si ngun ni àní titi dé pínpín ọkàn ati ẹ̀mí níyà, orike àti ọ̀rá inú egungun, oun si ni olùmọ̀ èrò ati ète ọkan. (Jer 23:29; Ef 6:17; 1 Kor 14:24,25.)

13. Kò si ẹ̀dá kan tí kò farahan niwaju rẹ̀, ṣugbọn ohun gbogbo ni ó wà níhòhò ti a si ṣípayá fun ojú rẹ̀, ẹni ti awa nbá lò. (Psm 33:13–15; Job 26:6.)

**Nipa jíjẹ́wọ́ Kristi ni a fi lè sunmọ Ọlọrun.**

14. Njẹ bi a ti ní Olórí Alufa nla kan, tí ó ti la awọn ọrun kọjá lọ, Jesu Ọmọ Ọlọrun, ẹ jẹ́ ki a di ijẹwọ wa mú şinşin. (Heb 3:1; 7:26; 10:23.)

15. Nitori a kò ni olori alufa tí kò lè ṣàì bá ni kẹ́dùn ninu ailera wa, ẹni tí a ti danwo lọ́nà gbogbo gẹgẹ bi àwa, ṣugbọn láìlẹ́ṣẹ̀. (Heb 2:18; 2 Kor 5:21; 1 Pet 2:22.)

16. Nitori naa ẹ jẹ ki a wá si ibi ìtẹ́ oore-ọfẹ pẹlu ìgboyà, ki a le ri aanu gba, ki a sì rí oore-ọ̀fẹ́ lati maa ranni lọ́wọ́ ní akoko ti ó wọ̀. (Ef 2:18.)

ORI 5.

**Kristi Olori Alufa ti a yàn lati ọdọ Ọlọrun wá.**

NITORI olori alufa kọọkan tí a yàn ninu awọn eniyan, ni a fi jẹ nitori iṣẹ́ ìsìn awọn eniyan si Ọlọrun lati maa mú ẹ̀bùn ati ẹbọ wá nitori ẹ̀ṣẹ̀. (Heb 8:3,4; 7:27.)

2. Ẹni ti o lè ba awọn alaimoye ati awọn ti o ti yapa kẹ́dùn, nitori a fi ailera yí oun náà ká pẹlu. (Heb 2:18; Jms 5:19; Heb 7:28.)

3. Nitori ìdí èyí ni ó ṣe nilati máa mú ẹbọ wá nitori èṣè rẹ̀, ati bẹ́ẹ̀ pẹlu, nitori ti awọn eniyan náà. (Heb 7:27; 9:7.)

4. Ko si ẹni ti o gba ọlá yìí fun ara rẹ̀, bikoṣe ẹni tí a pè lati ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá gégẹ́ bi a ti pe Aaroni. (2 Kro 26:18; Eks 28:1.)

5. Bẹẹ ni Kristi pẹlu kò si ṣe ara rẹ̀ logo lati jẹ́ Olórí Alufa; bikoṣe ẹni ti o wí fun ún pé, "Iwọ ni Ọmọ mi, loni ni mo bi ọ." (Jhn 8:54; Psm 2:7; Heb 1:1,5.)

6. Bi o ti wí pẹlu ní ibi miran pé, "Iwọ ni alufa títí lae ní titèlé apẹẹrẹ ti Melkisedeki." (Psm 110:4; Heb 7:17.)

7. Ni ìgbà ọjọ rẹ̀ ninu ara, o fi ẹkún rara ati omijé gbadura, tí ó si bẹ̀bẹ̀ lọdọ ẹni tí o le gbà a sílẹ̀ lọ́wọ́ ikú, a si gbóhùn rẹ̀ nitori ẹ̀mí ìbẹ̀rù-Ọlọrun rẹ̀. (Matt 26:39; 53:27,46; Mk 14:36; 15:34.)

8. Bi o ti jẹ́ Ọmọ tó , sibẹ ó kọ́ ìgbọràn nipa ohun tí o jìyà rẹ̀; (Heb 3:6; Filp 2:8.)

9. Bi a si ti sọ ọ di pípé, o wa di orisun ìgbàlà àìnípẹkun fún gbogbo awọn ti o ngbọ tirẹ̀: (Heb 2:10.)

10. Tí a yàn ní Olórí Alufa lati ọdọ Ọlọrun ní titèlé apẹẹrẹ ti Melkisedeki. (ẹsẹ 5,6.)

**Ibawi nitori ailoye awọn eniyan.**

11. Nipa èyí awa ní ohun púpọ̀ lati sọ, ti o si ṣòro lati túmọ̀, nitori pé ẹ yigbì ní gbígbọ́.

12. Nitori pe bayìí ó ti yẹ kí ẹ jẹ́ olukọni, ẹ tún wà ni ẹni tí ẹnikan yoò maa kọ́ ni ìbẹ̀rẹ̀ ìpìlẹ̀-ẹ̀kọ́ awọn ọ̀rọ̀ Ọlọrun, ẹ si tún di irú awọn tí ó nfẹ wàrà, tí wọn kò si fẹ́ ounjẹ líle. (Gal 4:3; Heb 6:1; A.A. 7:38; 1 Kor 3:2.)

13. Nitori olukuluku ẹni tí nmu wàrà jẹ́ alailoye ọ̀rọ̀ ododo: nitori ọmọ ọwọ́ ni. (1 Kor 3:1.)

14. Ṣugbọn ounjẹ líle ni fun awọn ti o dàgbà, awọn ẹni nipa ìrírí, tí wọn nlo ọgbọ́n wọn lati fi ìyàtọ̀ sáàrin rere ati buburu. (Isa 7:15.)

ORI 6.

**Ìkìlọ̀ saaju.**

NITORI naa, bi a ti nfi * alákọkọ́-kọ́ ẹ̀kọ́ Kristi sílẹ̀, ẹ jẹ́ ki a tẹsíwaju si jíjẹ́-pépé, láìtún ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ lati fi ìpìlẹ̀ ironúpìwàdà kúrò ninu òkú iṣẹ́ lélẹ̀, ati ìgbàgbọ́ siha ti Ọlọrun, (Heb 5:11-14.)

2. Ti ẹ̀kọ́ awọn baptisimu, ati ti ìgbọ́wọ́-léni, ti ajinde oku, ati ti ìdájọ́ ainipẹkun. (A.A. 19:3,4; 6:6.)

3. Eyi ni awa yoo si ṣe bi Ọlọrun bá yọ̀nda (A.A. 18:12.)

4. Nitori pe ko ṣeeṣe, fun awọn ti a ti là lójú lẹ́ẹ̀kan, ti wọn si ti tọ́ ẹ̀bùn ọ̀run wò, ti wọn sì ti di alábápín Ẹ̀mí Mímọ́, (Heb 10:26,32; Ef 2:8; Gal 3:2,5.)

5. Ti wọn sì tọ́ ọ̀rọ̀ rere Ọlọrun wò, ati agbara ayé ti nbọ, (Heb 2:5.)

6. Lati tún sọ wọn di ọ̀tun sì ìronupìwàdà bi wọn bá ṣubu kuro; nitori ti wọn tun kan Ọmọ Ọlọrun mọ́ àgbélèbú si ara wọn lọ́tun, wọ́n sì dojuti i nì gbangba. (Heb 10:26–29.)

7. Nitori ilẹ̀ tí o fi omi òjò tí nrọ̀ sórí rẹ̀ nigbagbogbo mu, tí ó si nhu ewébẹ̀ ti o dara fun awọn tí a ntìtorí wọn ro ó pẹlu, ngba ìbùkún lọwọ Ọlọrun. (Psm 65:10.)

8. Ṣugbọn bi o ba nhu ẹ̀gún ati òṣùṣù, yoò di kíkọ̀sílẹ̀, kò si jìnnà si fifi gégùn, opin eyi tí yoò jẹ fún ìjóná. (Gen 3:17,18.)

**A mu awọn onigbagbọ lọkan le.**

9. Ṣugbọn, olùfẹ́, awa ní igbagbọ ohun tí o dara jù bẹẹ lọ, ní ti yín, ati ohun tí o faramọ́ ìgbàlà, bi o tilẹ̀jẹ́ pe a nṣe bayìí sọ̀rọ̀.

10. Nitori Ọlọrun ki í ṣe alaiṣododo tí yoò fi gbàgbé iṣẹ́ yin ati ìfẹ́ tí ẹyin fihan sí orukọ rẹ̀, nipa iṣẹ́ iranṣẹ tí a ti ṣe fún awọn eniyan mimọ, tí ẹ si tún nṣe. (Matt 10:42; 25:40; 2 Tess 1:6,7; 1 Tess 1:3; Rom 15:25.)

---

(1-2) Alákọkọ́-kọ́ ẹ̀kọ́ Kristi ti eniyan lè kọ́ ti yoo fi ní òye wíwà ninu Kristi ati lati jogùn ijọba ọ̀run ni èyí ti Paulu mẹ́nuba nihin-ín yìí. (1). ẹ̀kọ́ ironúpìwàdà (2) igbàgbọ́ siha ti Ọlọrun (3) ẹ̀kọ́ awọn baptisimu méjèèji (Jhn 3:5) (4) ẹ̀kọ́ bi a ti ngbọ́wọ́léni fun iṣẹ́-iranṣẹ́, (5) Ajínde òkú ati (6) Idajọ́ àìnípẹ̀kun.

11. Awa si fẹ́ kí olukuluku yín maa fi irú aisinmi kannaà hàn, fun ẹkún idaniloju ireti titi de òpin: (Heb 3:6,14; Kol 2:2.)
12. Kí ẹ máṣe di onílọra, ṣugbọn alafarawe awọn tí wọn ti ipa igbagbọ ati sùúrù jogún awọn ileri. (Heb 10:36.)

**Ileri tí Ọlọrun ṣe fun Abrahamu kò yẹ̀.**

13. Nitori nigba ti Ọlọrun ṣe ileri fun Abrahamu, bi ko ti rí ẹni tí o pọ̀jù oun lati fi búra, o fi ara rẹ̀ bura, wí pé, (Gen 22:16,17; Lk 1:73.)
14. "Nitootọ ni bíbùkún emi ó bùkún fun ọ, ati ni bíbísí emi ó si mu ọ bísi i."
15. Bẹẹ naa si ni, lẹhin igba tí o fi suuru dúró, o ri ileri naa gbà.
16. Nitori eniyan a máa fi ẹni tí o pọju wọn bura: ibura náà a si fi opin si gbogbo ìjiyàn wọn fun ìfẹsẹ̀-mulẹ ọ̀rọ̀. (Gal 3:15; Eks 22:11.)
17. Ninu èyí ti, bi Ọlọrun ti nfẹ gidigidi lati fi aileyipada ète rẹ̀ hàn fun awọn ajogún ileri, o fi ibura sáarin wọn. (Heb 11:9; Psm 110:4.)
18. Pé, nipa ohun àìlèyípadà meji, ninu èyí ti kò lè ṣeeṣe fun Ọlọrun lati ṣèké, ki awa ti o ti sá sábẹ́ ààbò lè ni iṣírí tí o dájú lati di ireti ti a gbe kalẹ niwaju wa mú: (Tit 1:2; Heb 7:19.)
19. Èyí ti awa ní bi ìdákọ̀ró ọkàn, ireti tí ó dájú tí ó si duro ṣinṣin, ti o si wọ inu lọ́hùn lọ lẹhin aṣọ ìkelé; (Lef 16:2; Heb 9:7.)
20. Nibi ti aṣaaju wa ti wọ̀ lọ fún wa, àní Jesu, tí a fi jẹ Olori Alufa titi lae ní titẹlé àpẹẹrẹ ti Melkisedeki. (Heb 4:14; 5:6.)

ORI 7.

**Iṣẹ́ iranṣẹ Alufa Jesu gajù ti Melkisedeki lọ.**

NITORI Melkisedeki yìí, ọba Salẹmu, alufa Ọlọrun Ọga-ogo, ẹni tí o pade Abrahamu bi o ti npada bọ̀ lati ibi pipa awọn ọba, ti o si sure fún un. (Gen 14:18–20.)
2. Ẹni tí Abrahamu si pin ìdámẹ́wá ohun gbogbo fún; lọ́nà ekinni ninu itumọ rẹ̀, Ọba ododo, ati lẹhin naà pẹlu, ọba Salẹmu, tí í ṣe Ọba alaafía;
3. Láìni baba, láìni ìyá, láìni ìtàn ìran, bẹ́ẹ ni kò ni ìbẹ̀rẹ̀ ọjọ́ tabi òpin ọjọ́ ayé; ṣugbọn a ṣe é bi Ọmọ Ọlọrun; ó wa ní alufa títí. (ẹsẹ 6,28.)
4. Njẹ ẹ gba a rò bí ọkunrin yìí ti pọ̀ to, ẹni tí Abrahamu baba nla fi idamẹwa ninu awọn àṣàyàn ìkogun fún. (Gen 14:20.)
5. Ati nitootọ awọn tí o jẹ́ ọmọ Lefi, tí o gba oyè alufa, wọ́n ní àṣẹ lati maa gba idamẹwa lọwọ awọn eniyan gẹgẹ bi ofin, eyi yìí, lọwọ awọn arakunrin wọn, bí ó tilẹ̀ ti jẹ́ pé, wọn ti inu Abrahamu jade. (Num 18:21,26.)
6. Ṣugbọn oun ẹni tí a ko tilẹ̀ pìtàn ìran rẹ̀ lati ọdọ wọn wá, gba idamẹwa lọwọ Abrahamu, ó sì sure fún ẹni tí o gba ileri. (Gen 14:19; Rom 4:13.)
7. Lai si ìjiyàn rárá ẹni ti kò to ẹni ni a nsure fún lati ọdọ ẹni tí o ju ni.
8. Ati nihin, awọn ẹni kíkú gba idamẹwa; ṣugbọn níbẹ̀, ẹni tí a jẹri rẹ̀ pé o nbẹ láàyè nì. (Heb 5:6; 6:20.)
9. Ati bí a ti le wí, Lefi papa ti ngba idamẹwa, ti san idamẹwa nipasẹ Abrahamu.
10. Nitori o saa sì nbẹ ní inu baba rẹ̀, nigba ti Melkisedeki pade rẹ̀.

**Iṣẹ́ Alufa Aaroni jẹ́ èyí ti o ni òpin, ṣùgbọ́n tí Jesu wa títí laelae.**

11. Njẹ ìbáṣe pé pípé nbẹ nipa oyè alufa Lefi, (nitori pé labẹ rẹ̀ ni awọn eniyan gba òfin), kinni ó si tun kù mọ tí alufa miran ìbá fi dide ní títẹ̀lé apẹẹrẹ tí Melkisedeki, tí a ko si wi pé ní títẹ̀lé apẹẹrẹ tí Aaroni? (ẹsẹ 18,19; Heb 8:7; 10:1; ẹsẹ 17.)
12. Nitori pé bi a ti npàrọ̀ iṣẹ́ alufa, a kò sì lè ṣàì maa pàrọ̀ ofin.
13. Nitori ẹni tí a nsọ̀rọ̀ nkan wọnyìí nipa rẹ̀ jẹ́ ẹ̀yà míran, lati inu èyí tí ẹnikẹni kòì jọ́sìn rí nibi pẹpẹ. (ẹsẹ 14,11.)
14. Nitori ó hàn gbangba pé lati inu ẹ̀yà Juda ni Oluwa wa ti dide; nipa ẹ̀yà yìí Mose kò sọ ohunkohun niti awọn

alufa. (Isa 11:1; Matt 1:3; Luk 3:33; Rom 1:3; Ifh 5:5.)

15. O si tun hàn gbangba ju bẹẹ lọ bi ó ti jẹ pé alufa miran dide ni àpẹẹrẹ ti Melkisedeki.

16. Èyí tí a fi jẹ, kìí ṣe gẹ́gẹ́ bi ìlànà ofin nipa ti ara, bikoṣe nípa agbára ti ìyè ailopin. (Heb 9:10,14.)

17. Nitori a jẹri pé, "Iwọ ni alufa titi lae ni titẹlé àpẹẹrẹ ti Melkisedeki." (Psm 110:4; Heb 5:6; 6:20; ẹsẹ 21.)

18. Nitori a mú ofin iṣaaju kúrò, nitori ailera ati ailérè rẹ̀. (Rom 8:3; Gal 4:9.)

19. (Nitori ofin kò mu ohunkohun pé), a si mu ìrètí ti o dara jù wa nipa èyí tí awa nsunmọ Ọlọrun. (A.A. 13:39; Rom 3:20; Gal 2:16; Heb 9:9; 6:18; 8:6; 4:16.)

**Ṣiṣe iyebiye iṣẹ́ iranṣẹ ti Jesu Kristi.**

20. Niwọn bi o si ti ṣe pé ki i ṣe ni aibura ni.

21. Nitori awọn alufa tẹ́lẹ̀ jẹ oyè laisi ibura, Ṣugbọn ti oun jẹ́ pẹlu ibura nipa ẹni tí ó wí fún un pé, "Oluwa bura, ki yoò si yí padà, 'Iwọ ni alufa kan titi lae ni titẹ̀lé àpẹẹrẹ ti Melkisedeki:'" (Psm 110:4.)

22. Niwọn bẹẹ ni Jesu ti di onígbọ̀wọ́ majẹmu ti ó dara jù. (Heb 8:6; 9:15; 12:24.)

23. Ati nitootọ awọn pupọ ni a ti fi jẹ alufa, nitori wọn kò lè wà titi nitori ikú:

24. Ṣugbọn oun, nitori tí o wà titi lae, o ní oyè alufa ti a kò lè rọ nípò. (ẹsẹ 28.)

25. Nitori naà ó si le gbà wọ́n là pẹlu titi dé opin, ẹni tí o ba tọ Ọlọrun wá nipasẹ̀ rẹ̀, nitori tí o nbẹ láàyè títí lae lati maa bẹ̀bẹ̀ fun wọn. (ẹsẹ 19; Rom 8:34; Heb 9:24.)

26. Nitori pé irú Olori Alufa bẹẹ ni o yẹ wá, mímọ́, ailẹgan, ailéeri, ti a ya sọ́tọ̀ kuro laarin awọn ẹlẹṣẹ, ti a si gbéga ju awọn ọ̀run lọ; (Heb 4:15; 8:1.)

27. Ẹni tí kò ni lati maa kọ́ rúbọ lojojumọ, bi awọn olori alufa, fun ẹ̀ṣẹ̀ ti ara rẹ̀ naà, ati lẹhin naa fun ti awọn eniyan; nitori èyí ni ti o ṣe lẹ̀ẹ̀kanṣoṣo, nigba ti o fi ara rẹ̀ rúbọ. (Heb 5:1,3; 9:12; Ef 5:2; Heb 9:14,28.)

28. Nitori pé òfin a maa fi awọn eniyan tí ó ni ailera jẹ olori alufa; ṣugbọn ọ̀rọ̀ ti ibura, ti o ṣe lẹhin ofin, o fi Ọmọ jẹ, ẹni tí a sọ di pípé titi lae. (Heb 5:2; 1:2; 2:10.)

## ORI 8.

**Majẹmu titun dara ju majẹmu laelae.**

NISINSINYÌÍ, kókó ohun ti a nsọ nìyìí: Awa ni irú Olori Alufa bẹẹ, tí ó jokòó lọwọ ọ̀tún ìtẹ́ Ọlá-nla ninu awọn ọ̀run: (Heb 2:17; 1:3.)

2. Ìránṣẹ́ ibi mímọ́, ati ti àgọ́ tòótọ́, tí Oluwa pa, ki í ṣe eniyan. (Heb 9:11,24.)

3. Nitori a fi olori alufa kọọkan jẹ lati maa mú ẹ̀bùn wá lati maa rubọ: nitori naa olori alufa yìí pẹlu kò lè ṣàìní ohun tí yoo fi rubọ. (Heb 5:1; 9:14.)

4. Nisinsinyìí ibaṣe pé o nbẹ ni ayé, oun kì bá tilẹ̀ jẹ alufa, nitori awọn ti nfi ẹ̀bùn rúbọ gẹ́gẹ́ bi ofin nbẹ: (Heb 5:1.)

5. Awọn ẹni tí njọ́sìn fún àpẹẹrẹ ati òjìji awọn ọrun, bi a ti kọ́ Mose lati ọdọ Ọlọrun wá nigba ti o fẹ pa àgọ́: nitori o wi pé, "Kiyesii ki o ṣe ohun gbogbo gẹ́gẹ́ bí apẹẹrẹ ti a fihàn ọ lori òkè." (Kol 2:17; Heb 9:23; 10:1; Eks 25:40; Heb 11:7; 12:25.)

6. Ṣugbọn nisinsinyìí o ti gba iṣẹ́-iranṣẹ ti o ni ọlá jù, níwọ̀n bí o ti jẹ pé alarina majẹmu ti o dara ju ni i ṣe, èyí tí a fi ṣe ofin lórí ileri ti o sàn jù bẹ̀ẹ̀ lọ. (1 Tim 2:5; Heb 7:22.)

7. Nitori ibaṣepe majẹmu ìṣaaju nì kò ní àbùkù, njẹ a ki ìbá ti wa àyè fun ekeji. (Heb 7:11,18.)

**A gbe majẹmu titun lori ileri ti o dara julọ.**

8. Nitori ti o ri àbùkù lara wọn, o wi pe, "Kiyesi i ọjọ nbọ, ni Oluwa wí, ti emi o bá ile Israẹli ati ile Juda dá majẹmu titun. (Jer 31:31–34.)

9. Kì i ṣe gẹgẹ bi majẹmu tí mo ti bá

awọn baba wọn dá, lọjọ naà ti mo fà wọ́n lọwọ lati mú wọn jade kuro ni ilẹ Egipti; nitori tí wọn kò duro ninu majẹmu mi, emi kò si kà wọn sí, ni Oluwa wí. (Eks 19:5,6.)

10. Nitori eyi ni majẹmu tí emi o bá ilé Israẹli dá lẹhin awọn ọjọ wọnyìí, ni Oluwa wi; Emi ó fi ofin mi sí inu wọn, emi ó si kọ wọ́n sí ọkàn wọn, emi ó si maa jẹ́ Ọlọrun fún wọn, wọn ó si maa jẹ́ eniyan fun mi. (Heb 10:16; 2 Kor 3:3; Sek 8:8.)

11. Olukuluku ko ni tun maa kọ́ ara ìlú rẹ̀, tabi olukuluku arakunrin rẹ̀, pe, 'Mọ Oluwa': nitori pé gbogbo wọn ni yoo mọ̀ mí, lati kekere dé àgbà. (Isa 54:13; Jhn 6:45; 1 Jhn 2:27.)

12. Nitori pé emi o ṣàanu fún aiṣododo wọn, ati ẹ̀ṣẹ̀ wọn ati aiṣedeede wọn lemi ki yoò si rántí mọ́." (Heb 10:17.)

13. Ní èyí ti o wi pé, Majẹmu titun, o ti sọ ti iṣaaju di ti laelae. Ṣugbọn èyí tí ó ndi ti laelae tí ó si ngbó, o mura ati di asán. (2 Kor 5:17.)

ORI 9.

**Ìrúbọ majẹmu laelae wà fun ìgbà díẹ̀.**

BẸẸ ni majẹmu iṣaaju paapaa pẹlu ni ìlànà ìsin, ati ibi mímọ́ ti ayé yìí. (Eks 25:8.)

2. Nitori pé a pa àgọ́ kan; èyí ti iṣaaju ninu èyí ti ọ̀pá fitílà, ati tabili, ati àkàrà ifihan gbé wà, èyí tí a npè ni ibi mímọ́. (Eks 25:8,9,23–39.)

3. Ati lẹhin aṣọ ìkelé keji, oun ni àgọ́ ti a npe ni ibi mímọ́ jùlọ; (Eks 26:31–33.)

4. Ti o ni àwo turari wura, ati apoti majẹmu tí a fi wúrà bò yíká, ninu èyí tí ìkokò wura ti o ni mánnà gbé wà, ati ọ̀pá Aaroni ti o rudi, ati awọn walaa majẹmu; (Eks 30:1–5; 25:10; 16:32,33; Num 17:10.)

5. Ati lori rẹ̀ ni awọn kerubu ogo ti o ṣíjibo ìtẹ́ aanu; èyí tí a kò lè sọ̀rọ̀ rẹ̀ nisinsinyìí lọkọọkan; (Eks 25:17.)

6. Njẹ nigba ti a ti ṣe ètò nkan wọnyìí bayìí, awọn alufa a maa lọ nigbakugba sinu àgọ́ ekinni, wọn a maa ṣe iṣẹ́ ìsìn. (Num 28:3.)

7. Ṣugbọn sinu ekeji ni olori alufa nikan maa nlọ lẹkanṣoṣo lọ́dún, ki i ṣe láìsí ẹ̀jẹ̀ ti oun o fi rubọ fun ara rẹ̀, ati fun ìṣìnà awọn eniyan. (Lef 16:11; Eks 30:10; Heb 5:2,3.)

8. Ẹmi Mimọ ntọka èyí pé a kò ì tíì ṣí ọ̀nà ibi mimọ sílẹ̀ niwọn ìgbà tí àgọ́ ekini bá sì duro, (Heb 10:19,20; Jhn 14:6.)

9. (Eyi ti i ṣe apẹẹrẹ fun ìgbà isinsinyìí). Gẹgẹ bi ètò yìí, a nmu ẹ̀bùn ati ẹbọ wá, tí kò lè mú ẹ̀rí-ọkàn olùsìn di pípé, (Heb 11:19; 5:1; Gal 3:21.)

10. Èyí sì wa ninu ohun-jíjẹ ati ohun-mimu ati oniruuru ìwẹ̀, tíì iṣe ìlàna ti ara nìkan tí a fi lélẹ̀ titi fi di ìgbà atunṣe. (Lef 11:2; Kol 2:16; Heb 7:16.)

**A fi Kristi rubọ ayérayé sí Ọlọrun.**

11. Ṣugbọn nigba tí Kristi de bí Olori Alufa awọn ohun rere tí nbọ̀, nipaṣẹ àgọ́ ti o tobi ti o sì pé ju ti iṣaaju, (èyí tí a kò fi ọwọ́ pa, eyiyìí ni, ti ki i ṣe ti ẹ̀dá yìí,) (Heb 2:17; 10:1; 8:2.)

12. Bẹẹ ni ki i ṣe nipasẹ ẹ̀jẹ̀ ewurẹ ati ọmọ maalu, ṣugbọn nipa ẹ̀jẹ̀ oun tikararẹ, o wọ ibi mímọ́ lẹ̀ẹ̀kanṣoṣo, lẹhin ti o ti ri idande ainipẹkun gbà fun wa. (Heb 7:27; 10:4.)

13. Nitori bi ẹ̀jẹ̀ ewurẹ ati ti akọmalu ati eerú ẹgbọrọ abomalu ti a fi wọ́n awọn ti a ti sọ di aláìmọ́ ba nsọni-di-mímọ́ fun ìwẹ̀nùmọ̀ ara: (Num 19:9,17.)

14. Melomelo ni ẹ̀jẹ̀ Kristi, eni, nipa Ẹmí ayérayé, ti o fi ara rẹ̀ rúbọ sí Ọlọrun laini àbàwọn, yóo wẹ ẹ̀érí ọkàn yin nù kuro ninu òkù ẹ̀ṣẹ̀ lati sin Ọlọrun álàáyè? (1 Jhn 1:7; 1 Pet 3:18; Tit 2:14.)

**Majẹmu titun ni a muṣẹ nipa ikú Kristi.**

15. Ati nitori èyí ni o ṣe jẹ́ alarina majẹmu titun pé bí ikú ti nbẹ fun idande awọn irekọja tí o ti wà labẹ majẹmu iṣaaju, ki awọn tí a ti pè lè rí

ileri ogún ainipękun gbà. (1 Tim 2:5; Heb 3:1; 7:22.)

16. Nitori nibi ti ìwé ogún bá gbé wà, ikú ęni ti o șe e kò lè șe àìsí pęlu;

17. Nitori ìwé-ogun ní agbara lęhin ìgbà tí eniyan bá kú: nitori kò ní agbara rárá nigba ti ęni tí o șè e bá nbę lááyè. (Gal 3:15.)

18. Nitori naa ni a kò șe ya majęmu ișaaju paapaa sí mímǫ́ laisi ęjẹ̀. (Eks 24:6.)

19. Nitori nigba ti Mose ti sǫ gbogbo àșę nipa ti ofin fun gbogbo awǫn eniyan, o mu ęjẹ̀ ǫmǫ malu ati ti ewurę, pęlu omi, ati òwú òdòdó, ati ewé hissǫpu o si fi wǫ́n ati ìwé paapaa ati gbogbo eniyan. (Eks 24:6; Lef 14:4,7.)

20. Wí pé, "Èyí ni ęjẹ̀ majęmu tí Ǫlǫrun palașę fun yín;" (Eks 24:8; Matt 26:28.)

21. Bę ę gęgę ni o si fi ęjẹ̀ wǫ́n àgó, ati gbogbo ohun-èlò ìsìn. (Lef 8:15.)

22. O si fẹ́rẹ̀ jẹ́ ohun gbogbo ni a fi ęjẹ̀ wẹ̀nù gẹ́gẹ́ bi ofin; ati pe laisi ìtàjẹ̀ sílẹ̀ kò sí idariji. (Lef (17:11.)

**Kristi tó fún ębǫ ęșẹ̀ wa.**

23. Nitori náa a kò lè șàì fi iwǫnyìí wę awǫn apęęrę ohun ti nbę lǫrun mǫ́; șugbǫn ó yę kí a fi ębǫ tí ó sàn ju iwǫnyìí lǫ wę awǫn ohun ǫrun paapaa mǫ́. (Heb 8:5.)

24. Nitori Kristi kò wǫ ibi mímǫ́ tí a fi ǫwǫ́ șe lǫ ti i șe apęęrę ti otitǫ; șugbǫn ó lǫ si ǫrun paapaa, nisinsinyìí lati farahan ní iwaju Ǫlǫrun fun wa: (Heb 6:20; 8:2; 7:25; 1 Jhn 2:1.)

25. Kìí si i șe pé ki ó lè maa fi ara rè rúbǫ nigbakugba, bi olori alufa ti maa nwǫ inu ibi mímǫ lǫ lǫ́dǫǫdún ti oun pęlu ęjẹ̀ ti ki i șe tirè; (ęsę 7; Heb 10:19.)

26. Bi bęę ba ni oun ìbá tí maa jìyà nigbakugba lati ipilę ayé: șugbǫn nisinsinyìí ni o fi ara hàn lęękansǫșo lopin ayé lati mu ęșẹ̀ kúrò nipa ębǫ ara rẹ̀. (Heb 4:3; 7:27; 1:2.)

27. Níwǫ̀n bí a sì ti fi lélẹ̀ fún gbogbo eniyan lati kú lęękansǫșo, șugbǫn lęhin èyí idajǫ: (Gen 3:19; 2 Kor 5:10.)

28. Bęę ni Kristi pęlu lęhin tí a ti fi rubǫ lęękansǫșo lati ru ęșẹ̀ ǫpǫlǫpǫ, yoo farahan ní igba keji laisi ęșẹ̀ fun awǫn ti nwo ǫ̀nà rẹ̀ fún ìgbàlà. (Rom 6:10; 1 Pet 2:24; Tit 2:13.)

## ORI 10.

**Kristi fi ara rę rubǫ lęękansǫșo.**

NITORI ofin, bi o ti ní ojiji awǫn ohun rere ti nbǫ̀ ti ki i șe àwòrán tootǫ fún awǫn nkan naa, kò lè fi ębǫ kannaa tí wǫn nrú nigbagbogbo lǫdǫǫdun mu awǫn ti nwá sibẹ̀ di pipe. (Heb 9:9,11,23.)

2. Bikǫșe bęę, a kì ìbá tí dẹ́kun àti maa rú wǫn, nitori awǫn ti nsìn ki ìbá tí ní imǫ ęșẹ̀, nigba tí a ba ti wẹ̀ wǫ́n mǫ́ lęękansǫșo.

3. Șugbǫn ninu ębǫ wǫnyìí ni a nșe iranti ęșẹ̀ lǫdǫǫdun. (Heb 9:7.)

4. Nitori ko șeeșe fun ęjẹ̀ akǫ malu ati ti ewurę lati mu ęșẹ̀ kuro. (Mika 6:6,7.)

5. Nitori naa nigba ti Kristi wá sí ayé, ó wí pé, "Iwǫ kò fę ębǫ ati ǫrę, șugbǫn ara ni iwǫ ti pèsè fun mi: (Psm 40:6–8; Heb 1:6; 1 Pet 2:24.)

6. Ębǫ sisun ati ębǫ fun ęșẹ̀ ni iwǫ kò ní inú didun si.

7. Nigba naa ni mo wi pé, 'Kiyesi i (ninu ìwé-kíká ni a gbe kǫǫ́ nipa ti èmi) Mo dé lati șe ifę rę, Ǫlǫrun.'" (Jer 36:2.)

8. Nigba tí o wi ni ișaaju pé, "Iwǫ kò fẹ́ ębǫ ati ǫrę ati ębǫ sisun, ati ębǫ fun ęșẹ̀, bęę ni iwǫ kò ni inú dídùn si wǫn" (awǫn èyí ti a nrú gęgę bi òfin). (ęsę 5,6; Mk 12:33.)

9. Nigba naa ni o wi pé, "Kiyesi i, Mo dé lati șe ìfẹ́ rę Ǫlǫrun." O mu ti ișaaju kuro, ki a lè fi ìdí ekeji múlẹ̀. (ęsę 7.)

10. Nipa ifę naa ni a ti sǫ wá di mímǫ́ nipa ębǫ tí Jesu Kristi fi ara rẹ̀ rú lęękansǫșo. (Jhn 17:19; Heb 7:27; 1 Pet 2:24.)

**Ẹ̀rí si iṣẹ́ aṣepari Jesu.**

11. Ati olukuluku alufa si nduro lojoojumọ lati ṣiṣẹ́ ìsìn, o si nṣe ẹbọ kannaa nigbakugba, tí kò lè mu ẹ̀ṣẹ̀ kuro lae: (Heb 5:1; ẹsẹ 4.)

12. Ṣugbọn oun, lẹhin ìgbà tí o ti rú ẹbọ kan fun ẹ̀ṣẹ̀ titi lae, o jokòó lọ́wọ́ ọ̀tún Ọlọrun; (Heb 1:3.)

13. Lati ìgbà naa, ó nretí títí a o fi awọn ọ̀tá rẹ̀ ṣe apoti itisẹ̀ rẹ̀. (Psm 110:1; Heb 1:13.)

14. Nitori nipa ẹbọ kan a ti mu awọn ti a sọ di mimọ pé titi lae. (ẹsẹ 1.)

15. Ẹmi Mimọ si njẹri fun wa pẹlu: nitori lẹhin tí ó ti wí pé, (Heb 3:7.)

16. "Èyí ni majẹmu ti emi o ba wọn dá lẹhin awọn ọjọ́ wọnyìí, ni Oluwa wí, emi o fi òfin mi sí wọn ní ọkàn, inú wọn pẹlu ni emi o si kọ wọn sí; (Jer 31:33,34.)

17. Ẹ̀ṣẹ̀ wọn ati aiṣedeede wọn lemi ki yoo si rántí mọ́." (Heb 8:12.)

18. Ṣugbọn nibi tí imukuro iwọnyìí bá gbé wà, irubọ fun ẹ̀ṣẹ̀ kò sí mọ́.

**Didi igbagbọ wa mu ṣinṣin.**

19. Ará, njẹ bi a ti ni ìgboyà lati wọ inú ibi mímọ́ nipasẹ̀ ẹ̀jẹ̀ Jesu, (Ef 2:18; Heb 9:8,12.)

20. Nipa ọ̀nà titun ati ààyè, ti o yà sí mímọ́ fun wa, ati lati kọja aṣọ ìkelé, eyiyìí ni, ara rẹ̀;(Heb 9:8,3.)

21. Ati bí a ti ni alufa giga lori ilé Ọlọrun; (Heb 2:17; 1 Tim 3:15.)

22. Ẹ jẹ ki a fi otitọ ọkàn súnmọ́ tòsí ni ẹ̀kún igbagbọ, ki a si wẹ ọkàn wa mọ́ kúrò ninu ẹ̀rí ọkan buburu, ki a si fi omi mímọ́ wẹ ara wa nù. (Heb 4:16; Ef 3:12; Heb 9:14; Esk 36:25; Ef 5:26.)

23. Ẹ jẹ ki a di ìjẹ́wọ́ ireti wa mu ṣinṣin ni aiṣiyèmeji; (nitori pé olootọ ni ẹni ti o ṣe ileri) (Heb 4:14; 1 Kor 1:9.)

24. Ẹ jẹ́ kí a yẹ ara wa wò lati ru ara wa sí ìfẹ́ ati sí iṣẹ́ rere: (Heb 13:1; Tit 3:8.)

25. Ki a ma maa kọ ipejọpọ̀ ara wa sílẹ̀, gẹgẹ bi àṣà awọn ẹlomiran; ṣugbọn ki a maa gba ara ẹni niyanju; pẹlupẹlu bi ẹyin ti rii pé ọjọ́ naa nsunmọ etile. (A.A. 2:42; Heb 3:13; Filp 4:5.)

**Idajọ fun kíkùnà lati di Ọ̀rọ̀ Ọlọrun mu ṣinṣin.**

26. Nitori bí awa ba mọ̀ọ́mọ̀ dẹ́ṣẹ̀ lẹhin ìgbà ti awa ba ti gba ìmọ̀ otitọ kò tún sí ẹbọ fun ẹ̀ṣẹ̀ mọ́. (Num 15:30; 2 Pet 2:20; Heb 6:4–6.)

27. Bikoṣe ìrètí idajọ tí ó ba ni lẹ́rù, ati ti ibinu ti o múná, ti yoo pa awọn ọ̀tá run. (Heb 9:27; Isa 26:11.)

28. Ẹnikẹni ti o ba gan ofin Mose, ó kú laisi àánú nipa ẹ̀rí ẹni meji tabi mẹta: (Deut 17:2–6; Heb 2:2.)

29. Melomelo ni ẹ rò pe a o jẹ Oluwa rẹ̀ ni ìyà kikan, ẹni ti o tẹ Ọmọ Ọlọrun mọ́lẹ̀ ti o si ti ka ẹ̀jẹ̀ majẹmu ti a fi sọ ọ́ di mímọ́ si ohun àìmọ́, ti o si ti kẹgan Ẹmi oore-ọfẹ. (Heb 2:3; 6:6; 13:20; Ef 4:30; Heb 6:4.)

30. Nitori awa mọ ẹni ti o wi pé, "Ẹ̀san niti emi, Oluwa wi pe, Emi o gbẹ̀san." Ati pẹlu, "Oluwa yoo ṣe idajọ awọn eniyan rẹ̀." (Deut 32:35,36; Rom 12:19.)

31. Ohun ẹ̀rù ni lati ṣubú si ọwọ́ Ọlọrun alààyè.

**Ẹ̀rè nbẹ nikẹhin fun awọn ti kò fasẹhin.**

32. Ṣugbọn ẹ ranti ọjọ iṣaaju ninu èyí ti, nigba ti a ti ṣi yin loju, ẹ fi ara da wahala nla ti ìjìyà; (Heb 6:4; Filp 1:29,30.)

33. Lapakan, nigba tí a sọ yin di ìran wíwò nipa ẹ̀gàn ati ipọnju; ati lapakan, nigba ti ẹyin di ẹgbẹ awọn ti a ṣe bẹ́ẹ̀ si. (1 Kor 4:9; 1 Tess 2:14.)

34. Nitori ẹyin bá awọn ti o wa ninu ìdè kẹ́dùn, ẹ si fi ayọ̀ gba ìkólọ ẹrù yin, nitori ẹyin mọ ninu ara yin pé, ẹ ni ọrọ̀ ti o wà títí, ti o si dara jù bẹẹ lọ. (Heb 9:15.)

35. Nitori naa ẹ maṣe gbé igboya yín sọnu, èyí ti o ni èrè nla. (Heb 2:2.)

36. Nitori ẹyin ko le ṣe alaini suuru, nitori ìgbà ti ẹyin bá ti ṣe ìfẹ́ Ọlọrun

tán ki ẹyin le gba ileri naa. (Luk 21:19; Kol 3:24.)

37. Nitori ni ìwọ̀n ìgbà diẹ si i, Ẹni naa ti nbọ̀ yoo de, ki yoo si jafara. (Hab 2:3,4; Luk 18:8.)

38. Ṣugbọn olododo ni yoo yè nipa igbagbọ: ṣugbọn bi o ba fà sẹ́hìn, ọkàn mi ko ni inú dídùn si i. (Rom 1:17; Gal 3:11.)

39. Ṣugbọn awa kò sí ninu awọn tí nfà sẹhin sinu ègbé; bikoṣe ninu awọn ti o gbagbọ sí igbala ọkàn. (2 Pet 2:20; A.A. 16:30.)

## ORI 11.

**Itumọ igbagbọ.**

NJẸ igbagbọ ni idaniloju ohun ti a nreti, ijeri ohun ti a ko ri. (Rom 8:24; 2 Kor 4:18; 5:7.)

2. Nitori ninu rẹ ni awọn alagba (atijọ́) ni èrí rere. (ẹsẹ 4,39.)

3. Nipa igbagbọ ni a mọ̀ pé a ti dá ayé nipa ọ̀rọ̀ Ọlọrun; nitori naa kii ṣe ohun ti o hàn ni a fi dá ohun tí a nri. (Gal 1:1; Jhn 1:3; Heb 6:5.)

**Igbagbọ awọn baba nla wa.**

4. Nipa igbagbọ ni Abẹli rú ẹbọ si Ọlọrun tí ó sàn ju ti Kaini lọ, nipa èyí ti a jẹri rẹ pe olododo ni, Ọlọrun si njẹri ẹ̀bùn rẹ̀: ati nipa rẹ naa, bi o ti jẹ pe o ti ku, sibẹ o nfọhun. (Gen 4:4,10; 1 Jhn 3:12; Heb 12:24.)

5. Nipa igbagbọ ni a ṣi Enoku nipo padà kí o maṣe rí ikú; a ko si ri i, nitori ti Ọlọrun ṣi i nipo pada: nitori ṣaaju iṣipo pada rẹ̀, a jẹri yìí si i pe o wu Ọlọrun. (Gen 5:21–24.)

6. Ṣugbọn laisi igbagbọ ko ṣeéṣe lati wu u; nitori ẹni ti o ba ntọ Ọlọrun wá kò le ṣai gbagbọ pe o nbẹ, ati pé oun ni olùṣèsan fun awọn tí o fi ara balẹ̀ wá a. (Heb 7:19.)

7. Nipa igbagbọ ni Noah, nigba ti Ọlọrun kìlọ̀ ohun tí a koi tíì rí fun un o bẹru Ọlọrun, o si kan ọkọ̀ fún ìgbàlà ilé rẹ̀, nipa èyí ti o da ayé lẹbi, o si di ajogún ododo ti i ṣe nipa ìgbàgbọ́. (Gen 6:13–22.)

**Igbagbọ Abrahamu ati awọn ọmọ rẹ̀.**

8. Nipa igbagbọ ni Abrahamu, nigba ti a ti pe e lati jade lọ sí ibi tí oun yoo gbà fun ilẹ ìní, ó gbọ́, o si jade lọ, lai mọ ibi ti oun nrè. (Gen 12:1–4; A.A. 7:2–4.)

9. Nipa igbagbọ ni o ṣe àtìpó ni ilẹ ileri, bi ẹni pé ni ilẹ̀ àjèjì, o ngbe inu àgọ́, pẹlu Isaaki ati Jakọbu, awọn ajogun ileri kannaa pẹlu rẹ̀: (Gen 12:8; 18:1,9; Heb 6:17.)

10. Nitori tí ó nreti ìlú ti o ni ipilẹ; èyí ti Ọlọrun tẹ̀dó ti o si kọ́. (Heb 12:22; 13:14; Ifh 21:2.)

11. Nipa igbagbọ ni Sara tikararẹ pẹlu fi gba agbara lati lóyún, nigba ti o kọja ìgbà rẹ̀, nitori ti o ka ẹni ti o ṣe ileri sí olootọ́. (Gen 17:19; 18:11–14; 21:2.)

12. Nitori naa ni ọpọlọpọ ṣe ti ara ọkunrin kan jade, àní ara ẹni ti o dabi òkú, ọmọ bi ìràwọ̀ ojú ọ̀run lọpọlọpọ, ati bi iyanrìn etí òkun láìníye. (Rom 4:19; Gen 22:17; 32:12.)

13. Gbogbo awọn wọnyìí ni o kú ní igbagbọ, lai ri awọn ileri ~~naa~~ gbà, ṣugbọn ti wọn ri wọn ni òkèrè réré, ti wọn si gbá wọn mú, ti wọn si jẹ́wọ́ pé alejò ati àtìpó ni awọn lori ilẹ̀ ayé. (Gen 23:4; Psm 39:12.)

14. Nitori pé awọn ti o nsọ irú ohun bẹẹ fihàn gbangba pé, wọn nṣe afẹri ilu kan ti i ṣe tiwọn.

15. Ati nitootọ, ibaṣepe wọn fi ilú ti wọn ti jade wá sí ọkàn, wọn iba ti ri àyè pada.

16. Ṣugbọn nisinsinyìí wọ́n nfẹ ìlú kan tí o dara jù bẹẹ lọ, eyiyìí ni ti ọrun: nitori naa ojú wọn kò ti Ọlọrun, pé ki a maa pe oun ni Ọlọrun wọn; nitori tí o ti pèsè ìlú kan silẹ fun wọn. (Eks 3:6,15; Filp 3:20; Heb 13:14.)

17. Nipa igbagbọ ni Abrahamu, nigba ti a dan an wò, fi Isaaki rúbọ: ani oun ẹni ti o ri ileri gba mura tán lati fi ọmọ bíbí rẹ kanṣoṣo rúbọ, (Gen 22:1–10; Jms 2:21.)

18. Nipa ẹni ti a wi pé, "Ninu Isaaki

ni a o ti pe irú ọmọ rẹ̀:" (Gen 21:12; Rom 9:7.)

19. O si rò ó si pé Ọlọrun tilẹ le gbé e dide kuro ninu òkú, bẹẹ ni, bi a bá sọ ọ lọ́nà apẹẹrẹ, ó gbà á padà. (Rom (4:21.)

20. Nipa igbagbọ ni Isaaki sure fun Jakọbu ati Esau níti ohun ti nbọ.

21. Nipa igbagbọ ni Jakọbu, nigba ti o nku lọ, o sure fun awọn ọmọ Josẹfu ni ìkọ̀ọ̀kan; o si sìn ní itẹriba le orí ọ̀pá rẹ̀. (Gen 48:5; 16:20.)

22. Nipa igbagbọ ni Josẹfu, nigba ti o nku lọ, o ranti ijade lọ awọn ọmọ Israẹli; o si paṣẹ niti awọn egungun rẹ̀. (Gen 50:24,25; Eks 13:19.)

**Igbagbọ Mose.**

23. Nipa igbagbọ ni awọn obi Mose pa a mọ́ fun oṣù mẹta nigba ti a bi i, nitori ti wọn ri i ní arẹwà ọmọ; wọn kò sì bẹ̀rù aṣẹ̀ ọba. (Eks 2:2; 1:16.)

24. Nipa igbagbọ ni Mose, Nigba tí o dàgbà, ó kọ̀ ki a maa pe oun ní ọmọ ọmọ-binrin Farao; (Eks 2:10.)

25. Ó kúkú yàn lati maa ba awọn eniyan Ọlọrun jìyà, ju jíjẹ faaji ẹ̀ṣẹ̀ fun ìgbà diẹ. (ẹsẹ 37.)

26. O ka ẹ̀gàn Kristi si ọrọ̀ tí ó pọ̀ju awọn iṣura Egipti lọ: nitori ti o nwo èrè naa. (Heb 13:13; 2:2.)

27. Nipa igbagbọ ni o kọ Egipti silẹ laibẹru ibinu ọba: nitori ti o duro ṣinṣin bi ẹni ti o nri ẹni airi. (Eks 12:50,51; ẹsẹ 13.)

28. Nipa igbagbọ ni ó da àsè irekọja sílẹ̀, ati ìbùwọ́n ẹ̀jẹ̀, ki ẹni tí npa awọn akọbi ọmọ má baa fi ọwọ́ kan wọn. (Eks 12:21.)

**Igbagbọ awọn ọmọ Israẹli ati Rahabu.**

29. Nipa igbagbọ ni wọn la òkun pupa kọjá bi ẹni pé ni iyangbẹ ilẹ̀: ti awọn ara Egipti dánwo, ti wọn sì rì. (Eks 14:21–31.)

30. Nipa igbagbọ ni awọn odi Jeriko wo lulẹ̀, lẹhin ìgbà ti a yi wọn ká ni ijọ́ meje. (Jos 6:12–21.)

31. Nipa igbagbọ ni Rahabu panṣaga kò ṣègbé pẹlu awọn tí ko gbọ́ràn, nigba ti o tẹwọgba awọn amí ní alaafia. (Jos 2:9; 6:23; Jms 2:25.)

**Igbagbọ awọn onidajọ ati awọn Woli.**

32. Ẹwo ni emi o si tun maa wí si i? Nitori pé ìgbà yoo kunà fun mi lati sọ ti Gideoni, ati Baraku, ati Samsoni, ati Jẹfta; ati Dafidi, ati Samuẹli, ati ti awọn woli:

33. Awọn ẹni nipasẹ igbagbọ ti wọn ṣẹgun ilẹ̀ ọba, ti wọn ṣiṣẹ ododo, ti wọn gba ileri, ti wọn dí awọn kinniun lẹnu, (2 Sam 7:11; Ondj 14:5; 1 Sam 17:34; Dan 6:22.)

34. Ti wọn pa agbara iná, ti wọn bọ́ lọwọ ojú idà, ti a sọ di alagbara ninu ailera, ti wọn di akọni ni ìjà, wọn lé ogun awọn àjèjì sá. (2 A.Ọba 20:7; Ondj 15:8.)

35. Awọn obinrin ri òkú wọn gbà nipa ajinde: a si da awọn ẹlomiran lóró, wọ́n kọ̀ lati gba ìdásílẹ̀; ki wọn ba lè rí ajinde ti o dara jù gbà; (1 A.Ọba 17:22; A.A. 22:25.)

36. Awọn ẹlomiran sì rí ìjìyà ẹ̀sín, ati nínà,ati ju bẹẹ lọ,ti ìdè ati ti túbú: (Jer 20:2.)

37. A sọ wọ́n ni okuta, a fi ayùn rẹ́ wọn si méjì, a dán wọn wò a fi idà pa wọn: wọn rin kakiri ninu awọ agutan ati ninu awọ ewurẹ; wọn di alaini, olupọnju, ẹni ti a nda lóró; (1 A.Ọba 21:13; A.A 7:58; 2 A.Ọba 1:8.)

38. Awọn ẹni ti ayé ko yẹ fún: wọn nkiri ninu aṣálẹ̀, ati lori òkè, ati ninu ihò ati ninu abẹ́ ilẹ̀. (1 A.Ọba 18:4.)

39. Gbogbo awọn wọnyií ti a jẹri rere sí nipa igbagbọ, wọn kò sì ri ìlérí naa gbà:

40. Nitori Ọlọrun ti pèsè ohun ti o darajù sílẹ̀ fún wa, pé laisi wa, ki a má ṣe wọn pé. (Heb 5:9.)

## ORI 12.

**Kristi Olupilẹṣẹ ati Alaṣepe igbagbọ wa.**

NITORI naa bi a ti fi ikúukùu awọsanma ti o kún fun awọn ẹlẹri tó bayìí yí wa ká, ẹ jẹ ki a pa ohun idiwọ gbogbo tì si apakan, ati ẹ̀ṣẹ̀ ti o rọrun

lati dì mọ́ wa, ki a si maa fi sùúrù súré ìje tí a gbe ka iwájú wa, (1 Kor 9:24; Heb 10:36.)

2. Ki a maa wo Jesu Olùpilẹ̀ṣẹ̀ ati aláṣepé ìgbàgbọ́ wa; ẹni nitori ayọ̀ ti a gbe ka iwájú rẹ, tí o farada agbelebu laika ìtìjú sí, ti o si joko lọwọ ọ̀tún ìtẹ́ Ọlọrun. (Filp 2:8,9; Heb 1:3,13; 1 Pet 3:22.)

**Ìbáwí fun atunṣe idagbasókè ẹmí.**

3. Maa ro ti ẹni tí ó farada irú isọrọ-òdì yìí lati ọdọ awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ si ara rẹ̀, ki ẹ mábaa rẹ̀wẹ̀sì ni ọkàn yín, ki àárẹ̀ si mu yin. (Matt 10:24; Gal 6:9.)

4. Ẹyin kò saa tíì kọ ojú ìjà si ẹ̀ṣẹ̀ titi de tita ẹ̀jẹ̀ yin silẹ ninu ijakadi yín. (Heb 10:32–34; 1 Kor 10:13.)

5. Ẹyin si ti gbagbe ọ̀rọ̀ ìyànjú tí ó nba yin sọ̀rọ̀ bí ọmọ pé, "Ọmọ mi, ma ṣe alainani ibawi Oluwa, ki o ma si ṣe rẹ̀wẹ̀sì nigba ti a ba nti ọwọ́ rẹ̀ ba ọ wí: (Owe 3:11,12.)

6. Nitori pe ẹni ti Oluwa fẹ́, oun ni i bawi, a si maa na olukuluku ọmọ ti oun tẹ́wọ́gbà." (Psm 94:12; Jms 1:12.)

7. Ẹ maa ni suuru labẹ ibawi: Ọlọrun nba wa lò bi ọmọ ni; nitori pe ọmọ wo ni nbẹ ti baba kìí bawi? (Deut 8:5.)

8. Ṣugbọn bi ẹyin ba wà laisi ibawi, ninu èyí tí gbogbo eniyan ti jẹ alabapin, njẹ ọmọ àlè ni yín, ẹ kì í sì ṣe ọmọ. (1 Pet 5:9.)

9. Pẹlupẹlu awa ni baba wa nipa ti ara ti o ntọ́ wa, awa si nbu ọlá fún wọn: kò ha yẹ ki a kúkú tẹriba fun Baba awọn ẹ̀mí, ki a sì yè? (Luk 18:2; Num 16:22; Isa 38:16.)

10. Nitori wọ́n tọ́ wa fun ọjọ́ díẹ̀ bi o ba tí dara lójú wọn; ṣugbọn oun (tọ́ wa) fún èrè wa, ki awa le ṣe alabapin ìwà mimọ rẹ̀. (2 Pet 1:4.)

11. Gbogbo ibawi kò dabi ohun ayọ̀ nisinsinyìí bikoṣe ìbànújẹ́; ṣugbọn nikẹhin yoo so èso alaafia fun awọn ti a tọ́ nipa rẹ̀, àní èso ododo. (1 Pet 1:6; Jak 3:17,18.)

**Ìpèníjà si ìfaradà.**

12. Nitori naa ẹ na ọwọ́ tí o rọ, ati eékún ailera; (Isa 35:3.)

13. Ki ẹ si ṣe ipa-ọ̀nà ti o tọ́ fún ẹsẹ̀ yin, ki èyí ti o rọ má baa kuro lori ike ṣugbọn ki a kuku wò ó sàn. (Owe 4:26; Gal 6:1.)

14. Ẹ maa lepa alaafia pẹlu eniyan gbogbo, ati ìwà mímọ́, laisi eyiyìí kò sí ẹni tí yoo ri Oluwa: (Rom 14:19; 6:22; Matt 5:8.)

15. Ẹ maa kiyesara ki ẹnikẹni maṣe kùnà oore-ọfẹ Ọlọrun; ki "gbongbo ikoro" kan má ba hù sókè ki o si yọ yín lẹnu, ọpọlọpọ a si ti ipa rẹ̀ di àìmọ́. (Gal 5:4; Deut 29:18; Heb 3:12.)

16. Ki o má baa si àgbèrè kan tabi alaiwa-bi-Ọlọrun bi Esau, ẹni ti o ti-tori òkèlè ounjẹ kan ta ogún ìbí rẹ̀. (Gen 25:33.)

17. Nitori ẹyin mọ pe lẹhinnaa, nigba ti o fẹ lati jogún ìbùkún naa, a kọ̀ ó, nitori ko ri àyè ironupiwada, bi o tilẹ jẹ pé ó fi omijé wa a gidigidi. (Gen 27:30–40.)

**Ìkìlọ̀ ikẹhin lati máṣe pẹ̀hìndà kuro ninu ìgbàgbọ́ tòótọ́ ti Jesu Kristi.**

18. Nitori ẹyin kò wá òkè ti a le fi ọwọ́ kàn, ati ti iná ti njó, ati tí ìṣúdudu ati òkùnkùn, ati ìjì. (Eks 19:12–22; Deut 4:11.)

19. Ati ìró ìpè, ati ohùn ọ̀rọ̀, èyí ti awọn ti o gbọ́ bẹ̀bẹ̀ pé, ki a máṣe sọ ọ̀rọ̀ si i fun wọn mọ́: (Eks 20:19; Deut 5:5.)

20. Nitori pé ara wọn kò lè gba ohun tí ó palaṣẹ, "Bi o tilẹ jẹ ẹranko ni o farakan òkè naa, a o sọ ọ ni okuta, tabi a o gun un ní ọ̀kọ̀ pa," (Eks 19:12,13.)

21. Ìran naa si lẹ́rù to bẹẹ tí Mose wí pé, "ẹ̀rù ba mi gidigidi mo si wárìrì." (Eks 19:16.)

22. Ṣugbọn ẹ̀yin wá sí òkè Sioni, ati sí ìlú Ọlọrun alàáyè, ti Jerusalẹmu ti ọ̀run, ati si ẹgbẹ́ awọn angẹli àìníye, (Filp 3:20; Gal 4:26.)

23. Si àjọ nla ti ìjọ akọbi ti a ti kọ orukọ wọn ni ọ̀run, ati sọdọ Ọlọrun

onidajọ gbogbo eniyan, ati sọdọ awọn ẹ̀mí olootọ eniyan ti a ṣe ni àṣepé, (Luk 10:20; Filp 3:12;Ifh 14:1.)

24. Ati sọdọ Jesu alárinà majẹmu titun, ati si ibi ẹ̀jẹ̀ ìbùwọ́n ni, ti nsọrọ ohun tí ó dara ju ti Abẹli lọ. (1 Tim 2:5; Gen 4:10; Heb 11:4.)

25. Kiyesi i, ki ẹ maṣe kọ̀ ẹni ti nkilọ. Nitori bi awọn wọnyìí kò bá bọ́ nigba ti wọn kọ̀ ẹni ti nkilọ ni ayé, melomelo ni awa ki yoo bọ́, bi awa ba pẹhinda si ẹni ti nkilọ lati ọ̀run wá: (Heb 2:2,3; 8:5; 11:7.)

26. Ohùn ẹni ti o mi ayé nigba naa: ṣugbọn nisinsinyìí o ti ṣe ileri, wí pé, "Lẹ́ẹ̀kan si i emi ki yoo mi kìkì ayé nikan, ṣugbọn ọ̀run pẹlu." (Eks 19:18; Hag 2:6.)

27. Ati ọ̀rọ̀ yìí, "Lẹ́ẹ̀kan si i," ìtumọ̀ rẹ̀ ni, mímú awọn ohun wọ̀nyìí ti a nmì kuro, bi ohun ti a ti dá, ki awọn ohun tí a kò lè mì lè wà sibẹ. (1 Kor 7:31; 2 Pet 3:10.)

28. Nitori naa bi awa ti ngba ilẹ̀ ọba ti a kò lè mì, ẹ jẹ́ ki a ni oore-ọfẹ nipa èyí tí a fi lè maa sin Ọlọrun ni ìtẹ́wọ́gbà pẹlu ọ̀wọ̀ ati ìbẹ̀rù rẹ̀. (Dan 2:44; Heb 13:15.)

29. Nitori pe Ọlọrun wa, iná ti njonirun ni. (Deut 4:24.)

## ORI 13.

**Ohun ti o jẹ ọranyan fun awọn Onigbagbọ.**

KI ìfẹ ará o wà títí. (Rom 12:10; 1 Tess 4:9; 1 Pet 1:22.)

2. Ẹ maṣe gbagbe lati maa ṣe àlejò; nitori pe nipa bẹẹ ni awọn ẹlomiran ṣe awọn angẹli ní alejo láìmọ̀. (1 Pet 4:9; Gen 18:3.)

3. Ẹ maa ranti awọn òndè bi ẹni ti a dè pẹlu wọn, ati awọn tí a npọn loju bi ẹyin tikarayin pẹlu ti nbẹ ninu ara. (Matt 25:36; Kol 4:18.)

4. Ki igbeyawo lọ́lá laarin gbogbo eniyan, ki àkéte si jẹ alaileeri: nitori awọn àgbèrè ati awọn panṣaga ni Ọlọrun yoo dá lẹjọ. (1 Kor 6:9; Ifh 22:15.)

5. Ki ọkàn yin máṣe fà sí ìfẹ́ owó, ki ohun ti ẹ ní tó yin; nitori oun tikararẹ ti wi pé, "Emi kò jẹ fi ọ sílẹ̀, bẹẹ ni emi kò jẹ kọ̀ ọ́ silẹ." (Filp 4:11; Deut 31:6,8; Jos 1:5.)

6. Nitori naa ni awa ṣe nfi ìgboyà wi pé, "Oluwa ni oluranlọwọ mi, emi ki yoo bẹ̀rù; kinni eniyan lè ṣe sí mi?"

**Ṣíṣe afarawe awọn ti o ṣaaju ninu Igbagbọ.**

7. Ẹ maa ranti awọn ti wọn jẹ́ aṣaaju yín, tí wọn ti sọ ọ̀rọ̀ Ọlọrun fun yín; ki ẹ maa ro òpin ìwà-ayé wọn, ki ẹ si maa ṣe afarawe igbagbọ wọn. (ẹsẹ 17; Heb 6:12.)

8. Jesu Kristi ọkannaa ni lána, ati loni, ati titi lae. (Heb 1:12.)

9. Ẹ maṣe jẹ ki a fi oniruuru ati àjèjì ẹ̀kọ́ gbá yin kiri. Nitori o dara kí a mu yin lọ́kàn le nipa oore-ọfẹ, ki i ṣe nipa ounjẹ ninu èyí tí awọn tí ó ti rìn ninu wọn kò ní èrè. (Ef 4:14; Kol 2:7,16.)

10. Awa ní pẹpẹ kan, nibi èyí tí awọn ti nsin àgọ́ kò ni agbara lati maa jẹ. (1 Kor 9:13; 10:18.)

11. Nitori nigba ti olori alufa bá mú ẹ̀jẹ̀ awọn ẹran wá si ibi-mímọ́ gẹgẹ bi ìrúbọ ẹ̀ṣẹ̀, òkú awọn ẹran naa ni a o sun lẹhin ibùdó. (Eks 29:14; Lef 16:27.)

12. Nitori naa Jesu pẹlu, ki o le fi ẹ̀jẹ̀ ara rẹ̀ sọ awọn eniyan di mímọ́, ó jìyà lẹhin ibodè. (Jhn 19:17.)

13. Nitori naa ẹ jẹ ki a jade tọ̀ ọ́ lọ lẹhin ibùdó, ki a maa ru ẹ̀gàn rẹ̀. (Heb 11:26.)

14. Nitori pé awa ko ni ìlú tí o wa titi nihin, ṣugbọn awa nwá èyí tí nbọ. (Filp 3:20; Heb 10:34; 12:22.)

15. Njẹ nipasẹ rẹ̀, ẹ jẹ́ ki a maa rú ẹbọ ìyìn si Ọlọrun nigbagbogbo, eyiyìí ni èso ètè wa, ti njẹ́wọ́ orukọ rẹ̀. (1 Pet 2:5; Isa 57:9; Hos 14:2.)

16. Ṣugbọn ẹ maṣe gbagbe lati maa ṣoore ati lati maa pín funni nitori irú ẹbọ wọnyìí ni inu Ọlọrun dùn si jọjọ.

17. Ẹ maa gbọ́ ti awọn tí nṣe olori yín, ki ẹ si maa tẹriba fún wọn: nitori wọn nṣọ́ ẹ̀ṣọ́ nitori ọkàn yín, bi awọn ti

yoo ṣe iṣiro, ki wọn lè fi ayọ̀ ṣe èyí, ki i ṣe pẹlu ibanujẹ, nitori èyi yií yoo jẹ ailere fun yin. (Isa 62:6; A.A. 20:28.)

**Ibeere fun adura.**

18. Ẹ maa gbadura fun wa: nitori awa gbagbọ pé awa ni ẹ̀rí-ọkàn rere, a si nfẹ lati maa huwa titọ́ ninu ohun gbogbo. (1 Tess 5:25; A.A. 24:16.)

19. Ṣugbọn emi nbẹ yín gidigidi si i lati maa ṣe èyí, kí a ba lè tètè fi mí fun yin pada. (Film 22.)

**Gbigba ọ̀rọ̀ Ìyànú naa ati oore-ọ̀fẹ́.**

20. Njẹ Ọlọrun alaafia, ẹni tí o tun mu olùṣọ́-agutan nla ti awọn agutan, ti inu òkú wá, nipa ẹ̀jẹ̀ majẹmu ayérayé, àní Oluwa wa Jesu. (Rom 15:33; Sek 9:11.)

21. Ki o mu yin pé ninu iṣẹ́ rere gbogbo lati ṣe ìfẹ́ rẹ̀, ki o maa ṣiṣẹ ohun ti i ṣe itẹwọgba niwaju rẹ̀ ninu yín nipasẹ Jesu Kristi; ẹni tí ogo wà fún lae ati laelae. Amin. (1 Pet 5:10; Filp 2:13.)

22. Emi si nbẹ̀ yin, ará, ẹ gba ọ̀rọ̀ iyanju mi; nitori ìwé kukuru ni mo kọ si yin.

23. Ẹ mọ pe a dá Timoteu arakunrin wa silẹ̀; bí ó ba tètè de, emi pẹlu rẹ̀ yoò ri yín. (1 Tess 3:2; 1 Tim 6:12.)

24. Ẹ ki gbogbo awọn ti nṣe olori yin, ati gbogbo awọn eniyan mímọ́. Awọn tí o ti Itali wá ki yín. (ẹsẹ 7.)

25. Ki oore-ọfẹ wà pẹlu gbogbo yín. Amin. (Kol 4:18; Tit 3:15.)

59

# JEMISI

**(A.D. 60)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

JEMISI, iransẹ Ọlọrun ati ti Jesu Kristi Oluwa, si awọn ẹ̀yà mejila ti o tuka kiri, alaafia (A.A. 12:17; Tit 1:1; A.A. 20:7; Deut 32:26; Jhn 7:35; 1 Pet 1:1.)

**Isin otitọ ti a jẹri rẹ nipa fifi ara da ìṣòro.**

2. Ẹyin ará mi, nigba ti ẹyin ba bọ sinu onirúurú ìdánwò, ẹ ka gbogbo rẹ̀ si ayọ̀. (Matt 5:12; Heb 10:34; 1 Pet 1:6.)

3. Ki ẹ si mọ̀ pe ìdánwò igbagbọ yin nsiṣẹ suuru (Rom 5:3.)

4. Ṣugbọn ẹ jẹ ki suuru ṣe iṣẹ aṣepé, ki ẹyin lè jẹ pipe ati àìlábùkù, ki o má ku ohun kan fun ẹnikẹni. (Kol 4:12; 1 Tess 5:23.)

5. Bi o ba ku ọgbọ́n fun ẹnikẹni, ki o bèèrè lọwọ Ọlọrun, ẹni ti nfifun gbogbo eniyan lọpọlọpọ laisi ẹ̀gàn; a o si fifun un. (1 A.Ọba 3:9; Owe 2:3; 1 Jhn 5:14.)

6. Ṣugbọn ki o bèèrè ni igbagbọ, ni aiṣiyèméjì rárá. Nitori ẹni ti o nṣiyèméjì dabi ìgbì omi òkun, ti nti ọwọ́ afẹ́fẹ́ bì siwa bì sẹ́hìn ti a si nrú soke. (Mk 11:24.)

7. Nitori ki irú eniyan bẹẹ máṣe rò pe, oun yoo ri ohunkohun gba lọwọ Oluwa, (Jak 4:8.)

8. Eniyan oniyèméjì, alailèduro ṣinṣin ninu ọ̀nà rẹ̀ gbogbo.

9. Jẹ́ ki arakunrin ti i ṣe talaka maa ṣogo ninu ìgbega rẹ̀.

10. Ati ọlọrọ, ninu irẹsílẹ̀ rẹ̀, nitori bi ìtànná koriko ni yoo kọja lọ. (1 Kor 7:31.)

11. Nitori ti òòrùn yọ pẹlu mímúná ìgbona rẹ̀, o si gbẹ koriko; itanna rẹ̀ sì rẹ̀ dànù, ẹwà rẹ̀ si parun: bẹẹ pẹlu ni ọlọ́rọ̀ yoo ṣ̀ègbé ninu ilepa rẹ̀. (Isa 40:6–8; Psm 102:4,11.)

12. Ibukun ni fun ọkunrin ti o fi ọkàn rán ìdánwò; nitori nigba ti o bá yege, yoo gba ade ìyè, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ. (Heb 12:5; Jms 2:5.)

13. Ki ẹnikẹni ti a danwo maṣe wi